# ISỌJI NI JUDA NI AKOKO IJỌBA HẸSEKIAH

**2 Kronika 29:1-36**

**ẸKỌ 339 --- FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Ibukún ni fun awọn ti npa idajọ mọ́, ati ẹniti nṣe ododo ni igbagbogbo" (Orin Dafidi 106:3).**

### Ipo Buburu ti Juda Wa

Ahasi Ọba ti fi ijọba Juda si ipo ibanujẹ. O gbe isìn ibọrịṣa kalẹ; kò si si igba kan ninu gbogbo akoko ti o fi jọba ti o ṣe ohun rere kan ti o le mu ibukún wa sori awọn eniyan ti o wa labẹ ijọba rẹ. Nitori ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ati nitori ẹ̀ṣẹ awọn eniyan rẹ, Ọlọrun mu ki awọn orilẹ-ède miiran bori wọn. Ni akoko kan awon ọmọ-ogun Israẹli pa iwọn ọkẹ mẹfa (120,000) ọkunrin Juda ninu ogun, wọn si kó ọkẹ mẹwaa (200,000) obinrin ati ọmọde ni igbekun. Lẹyin eyi, awọn ara Edomu tun kó awọn ara Juda ni igbèkun. Awọn Filistini pẹlu si gba ọ̀pọlọpọ ninu ilẹ Juda wọn si n gbe ibẹ. Gbogbo wahala yii de ba Juda nitori ti Ahasi ọba mu awọn eniyan wọnyi dẹ̀ṣẹ.

Ipọnju de ba awọn eniyan wọnyi nitori pe wọn ti kẹyin si Ọlọrun. A kà ninu Iwe Owe pe: "Oye rere fi ojurere fun ni; ṣugbọn ọ̀na awọn olurekọja ṣoro" (Owe 13:15). Wolii Isaiah sọ bayi pe: "Alafia kò si fun awọn enia buburu, li OLUWA wi" (Isaiah 48:22). Kò si alaafia tootọ ninu ayé fun awọn ti o kọ̀ Oluwa silẹ.

Ọlọrun ti ṣeleri pe bi eniyan ba ke pe Oun nigba ipọnju, Oun yoo gbà wọ́n, Oun yoo sọ ibanujẹ wọn di orin ayọ̀. Oun yoo gbà wọn kuro ninu ipọnju, yoo si fun wọn layọ. Ṣugbọn wọn ni lati tọ Ọ wa pẹlu ironupiwada, wọn ni lati kẹdun pe wọn ti dẹ̀ṣẹ si I ati pe wọn ti ṣe tan lati kọ ẹ̀ṣẹ wọn silẹ.

### Ibẹrẹ Ijọba Hẹsekiah

Ahasi ọba ni ọmọkunrin kan ti a n pe ni Hẹsekiah, ẹni ti kò dabi baba rẹ̀ rara. Nigba ti Hẹsekiah di ọba, o n fẹ ni ibukun ti i ṣe ti awọn ti n sin Ọlorun, o si n fẹ ki awọn eniyan rẹ̀ ni alaafia. Ẹni ọdun mẹẹdọgbọn pere ni nigba ti o jọba, ṣugbọn o ti mọ̀ riri isin Ọlọrun. O ṣe eyi ti o tọ́ loju Oluwa, gẹgẹ bi Dafidi Ọba rere ti ṣe.

A kò mọ̀ bi Hẹsekiah ṣe ni imọ̀ nipa Ọlọrun nigba ti gbogbo eniyan, ati baba rẹ̀ paapaa, jẹ́ abọrịṣa, ti wọn tilẹ n fi ọmọ wọn paapaa rú ẹbọ sisun si orịṣa. O le jẹ pe o ti kà Iwe Ofin ti ọba kọọkan ni lati ni ni arọwọto rẹ̀ ti o si ni lati fi ọwọ ara rẹ̀ kọ́ ẹ̀dà rẹ̀. Ki a ma fa ọ̀rọ gùn, o ni imọ̀ Ọlọrun, ọkàn rẹ̀ n fẹ lati ṣe ohun ti o tọ́ ati lati sin gẹgẹ bi Ọlọrun ti fi lelẹ.

Ni ọdun kin-in-ni ijọba Hẹsekiah, o bẹ̀rẹ si i ṣe ayipada nipa titún ile Oluwa ṣe. Ni gbogbo ọdun mẹrindinlogun ti baba rẹ̀ fi jọba, awọn eniyan kò lọ si ile Ọlọrun rara bẹẹni wọn kò bikita fun awọn ohun ti i ṣe ti Ọlọrun. Iwọ naa gba eyiro bi Tẹmpili yoo ti kun fun eeri tó ti yoo si bajẹ to ni gbogbo akoko yii. Ahasi Ọba tilẹ ti kó pupọ ninu awọn ohun-elo ti a n lò ninu iṣẹ-isin, o ti ké wọn wẹ́wẹ; o tilẹ gbé ọ̀kan ninu awọn pẹpẹ Ọlọrun lati lo o fun ibọrịṣa, o huwa iwọsi si Ọlọrun lọpọlọpọ.

### Kò si Ina

Laaarin gbogbo ọdun wọnyi, iná ti o wà ninu Tẹmpili ti kú. Iwọ ha kọja lara ile-isin kan ti a kò lò mọ ti koriko ti hù ninu ọgba rẹ̀, ti digi oju ferese rẹ̀ si ti fọ́ wẹ́wẹ? Iwọ ha ti i kọja lara ile-isin bẹẹ li oru nigba pupọ lai si itanṣan imọlẹ nibẹ rara? Eyi kò ha ba ni ninu jẹ́? Iwọ ha woye bi yoo ti buru jai to bi gbogbo ile-isin ba wà lokunkun ti a si ti kọ̀ wọn silẹ patapata?

Awọn eniyan kan wà lọjọ oni ti wọn kò fẹ ki ẹnikẹni ki o sin Ọlọrun rara. Wọn n fẹ lati ti ilẹkun gbogbo ile-isin, ki won si pa gbogbo iná ti o wà nibẹ. Wo bi ayé yoo ti ṣokunkun to bi kò ba si ẹni kan ti n sin Jesu rara! Jesu ni Imọlẹ aye. Jesu mu imọlẹ ati ifẹ wá si ayé. Jesu ni orisun gbogbo ayọ tootọ.

### A pe awọn Alufaa ati awọn Ọmọ Lefi

Hẹsekiah ké si awọn alufaa ati awọn ọmọ Lefi ki wọn ya ara wọn si mimọ́ fun iṣẹ-isin Ọlọrun. O ṣeeṣe ki diẹ ninu awọn alufa yii ti maa sin orịṣa pẹlu. Wọn ki yoo le wà ni ipo ti wọn yoo fi le sin

Ọlọrun. Nigba ti wọn kó ara wọn jọ, Hẹsekiah sọ nipa iwa buburu awọn baba wọn ati iwa buburu ti o wà ni ilẹ naa. "Awọn baba wa sa ti dẹṣẹ, nwọn si ti ṣe ibi li oju OLUWA Ọlọrun wa." O fi ye wọn pe eyi ni eredi rẹ ti ipọnju nla fi de ba wọn. Awọn orilẹ-ède ti o yi wọn ka n yọ ṣuti si wọn, wọn si n fi wọn ṣe ẹlẹya, ani awọn ti a pe ni eniyan Ọlọrun.

O yẹ ki awa ti a n pe ara wa ni ọmọ Ọlọrun maa gbé igbesi-ayé iwa-bi-Ọlọrun ki awọn araye le mọ̀ pe awa jẹ ti Ọlọrun nitootọ! Bi wọn ko ba ri ẹwa Jesu ninu wa, awa ki i ṣe ọmọ Rẹ̀ nigba naa.

**Majẹmu Hẹsekiah**

Hẹsekiah n fẹ ri oju-rere Ọlọrun, o si ṣetan lati ṣe ohunkohun ti yoo gba a lati ni ibukun Ọlọrun. O ṣetan lati jẹwọ ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ati ti awọn eniyan rẹ̀, o ṣetan lati rubọ ati lati fi ara rẹ̀ ji fun Oluwa ati lati le ri idariji gbà. O rán awọn ọmọ Lefi leti pe Ọlọrun ti yàn wọn lati ma ṣe iṣẹ iranṣẹ ni Tẹmpili. Awọn ẹya Lefi ni o jade wa si iha ti Oluwa ni akoko ti Aarọni fi yá ẹgbọrọ-maluu wura, nigba kin-in-ni ti Israẹli kọ yi pada si ibọriṣa. Lati igba naa ni awọn ọmọ Lefi ti ni àye pataki ninu iṣẹ-isin Ọlọrun; Hẹsekiah si tun n ke si wọn lakoko yii lati dide lati ṣe iranwọ fun Oluwa.

Awọn ọmọ Lefi ati awọn alufaa fara mọ́ ohun gbogbo ti Hẹsekiah sọ. Wọn kọ́ wẹ ara wọn mọ́; wọn si mu ki ọkàn wọn ṣe deedee pẹlu Ọlọrun, lẹyin naa wọn bẹrẹ si i gbá ile Oluwa.

Nigba ti a ba wá lati sin Ọlọrun, a gbọdọ kọ ẹ̀ṣẹ wa silẹ ki a si wẹ̀ wá mọ́ kuro ninu ọ̀na buburu wa nipa gbigbadura si Jesu pe ki O mu ẹ̀ṣẹ wa kuro. Nigba ti a ba sin Ọlọrun pẹlu ọkàn mimọ́, isin wa ati ọrẹ wa yoo jẹ́ itẹwọgba niwaju Ọlọrun.

**Ile ti o Mọ́**

Gbogbo iṣẹ gbigbá ile Oluwa pari ni ọjọ kẹrindinlogun. Awọn ọmọ Lefi wọle tọ ọba lọ wọn si wi pe: "Awa ti gbá ile OLUWA mọ́, ati pẹpẹ ẹbọ sisun, pẹlu gbogbo ohun-elo rẹ̀, ati tabili akara-ifihan, pẹlu gbogbo ohun-elo rẹ̀. Pẹlu-pẹlu gbogbo ohun-elo, ti Ahasi, ọba, ti sọ di alaimọ́ ninu ẹ̀ṣẹ rẹ̀, li akokò ijọba rẹ̀, li awa ti pese ti awa si ti yà si mimọ́, si kiyesi i nwọn mbẹ niwaju pẹpẹ OLUWA."

Eyi ni ohun ti Hẹsekiah fẹ́ gbọ́. Wo bi inu rẹ̀ ti dùn toólati ri i pe iṣẹ isin tootọ tun le bẹrẹ lọtun ni ilẹ Juda! Ni kutukutu owurọ o dide o si kó awọn alaṣẹ ilu jọ, o si lọ si ile Oluwa. Nibẹ ni awọn alufaa si fi ẹran rubọ nitori ẹ̀ṣẹ ọba ati ti awọn eniyan naa, gẹgẹ bi ilana Ofin Mose.

**Orin Iyin**

Idile kan wà laaarin awọn ọmọ Lefi ti a ti yàn lati jẹ́ alo-ohun-elo-orin ati akọrin ninu Tẹmpili. Awọn pẹlu ti mura tan lati ṣe ipa ti wọn ninu iṣẹ-isin Ọlọrun. "Nigbati ẹbọ sisun na si bẹ̀rẹ, orin OLUWA bẹ̀rẹ pẹlu ipè ati pẹlu ohun-elo orin Dafidi, ọba Israẹli." Gbogbo ijọ eniyan naa si wolẹ sin, awọn akọrin, n kọrin, ipè si n dún: nnkan wọnyi si n lọ bẹẹ titi ẹbọ sisun naa fi pari. A kà ninu Majẹmu Titun pe, "Ninu ohun gbogbo, nipa adura ati ẹbẹ pẹlu idupẹ, ẹ mã fi ibere nyin hàn fun Ọlọrun" (Filippi 4:6).

Wo bi ayọ ti pọ to ni ọkan awọn eniyan naa! Lẹẹkan si i wọn tun le kọrin. Lọjọ oni isin Igbagbọ nikan ṣoṣo ni isin ti a ti maa n kọrin. Awọn ẹsin miiran le ni orin arò ati ègbè wọn ti o dà bi orin ọ̀fọ, ṣugbọn fifi ayọ ati inu didun kọrin jẹ ami kan ti a fi n mọ Onigbagbọ̀.

Bawo ni inu awọn eniyan Juda wọnyi ti dun to bi wọn ti n kọrin iyin si Ọlọrun Ọrun. Wọn tẹri wọn ba niwaju Rẹ̀, awọn akọrin wọn "si fi inu-didùn kọrin iyin, nwọn si tẹri wọn ba, nwọn si sin." Wo bi ọjọ naa ti jẹ ọjọ ayọ to ni Juda! A ti yi ọkàn awọn eniyan wọnyi kuro ninu ibọriṣa ati iwa buburu, wọn si ti ri idariji gbà lọdọ Ọlọrun.

**Idupẹ**

Nisisiyii ti Ọlọrun ti tú ibukun nlanla yii da sori awọn eniyan yii, wọn ni lati wi pe, "A dupẹ Ọlọrun." Nitori naa Hẹsekiah pe awọn alufaa lati mu ọrẹ-ọpẹ, ati ẹbọ-sisun ti iyasi-mimọ́ wọn wá. Ọpọlọpọ ẹbọ ni awọn eniyan ti o fi tọkàntọkàn yi pada si Ọlọrun mú wá, to bẹẹ ti awọn alufaa kò tó lati boju to awọn ẹbọ wọnyi. Ki i ṣe gbogbo awọn alufaa ni o ti ya ara wọn si mimọ́ fun Oluwa. "Awọn ọmọ Lefi ṣe olõtọ li ọkàn jù awọn alufa lọ lati yà ara wọn si mimọ́." Ohun ẹ̀dun ni lati ri i nigba miiran

pe awọn eniyan ti o fẹ Ọlọrun tọkantọkan ti wọn si n fẹ mọ gbogbo Ọrọ Ọlọrun a saba maa n ni ijatilẹ lọdọ awọn alufaa ti kò waasu gbogbo otitọ Ọrọ Ọlọrun ti wọn kò si fi ọwọ danindanin mú ọ̀ran iwa mimọ́.

Awọn eniyan ti o layọ ni awọn wọnni ti n ṣiṣẹ fun Ọlọrun pẹlu iṣọkan igbagbọ́; ti gbogbo wọn si jumọ n sin Ọlọrun lai jẹ ki ohunkohun ti i ṣe ohun ibajẹ ayé wọ inu igbesi-ayé ati iṣẹ-isin wọn. Ki Ọlọrun ran olukuluku wa lọwọ lati fi ohun mimọ́ ti Ọlọrun si ipo kin-in-ni ninu igbesi-ayé wa ki a ba le ni idapọ pẹlu Rẹ̀.

**AWỌN IBEERE**

1 Iru ọba wo ni Ahasi i ṣe?

2 Bawo ni Hesekiah ṣe bẹrẹ ijọba rẹ̀?

3 Ọmọ ọdun meloo ni Hẹsekiah nigba ti o bẹrẹ si jọba?

4 Ki ni ohun kin-in-ni ti awọn alufaa ati awọn ọmọ Lefi ṣe lẹyin ti wọn ti ya ara wọn si mimọ́?

5 Sọ nipa isin ti o tẹle gbigbá Tẹmpili?

6 Ipa wo ni awọn akọrin ati awọn alo-ohun-elo orin kó ninu iṣẹ-isin?

7 Awọn ẹlẹsin wo ni o maa n kọrin?

8 Awọn eniyan wo lo ni ayọ?